# ELETI OFE

'A-NJU - WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL. XIV NO 870 SATURDAY MAY 25—MAY 31 KỌBỌ MEJI (2D) 1963


EYI ARA !

# Baba Kan Gba Iyawo Lowo Omo Re

IJẸBU-ODE—Gbogbo awọn ti o wa si Kotu awọn ọlọpa ni iwaju adajọ-agba, Oloye O. Ade Okenla n rẹrin titi nigbati nwọn gbọ ejọ ti ọkunrin kan ti o njẹ Ezekiel Adewunmi bẹrẹ ro ejọ lori obinrin ti o gba lọwọ ọmọ bibi inu rẹ.

Adewunmi ni Iyabọ Salami ni orukọ iyawo titun ti on ṣẹṣẹ gba na njẹ. O ni ọmọ on ti o njẹ Salami Abudu ni o fẹ obinrin na, o si jẹ iyawo ti o ni iwa daradara pupọ ṣugbọn ọmọ on ko tọju rẹ to.

Adajọ ni ọkunrin na bi iru iwa bayi ba jẹ aṣa ilu wọn; o dahun, o ni on ko fẹ ki ẹlomiran fi obinrin na ṣe ifaje ni o jẹki on gba lọwọ ọmọ on nitoripe oni lati kọ ẹkọ rẹ na silẹ nipa iwa ti o nhu sii.

Nwọn si wa lenu wọn, san owo ikọsilẹ fun ọmọ rẹ nisisiyi.

## Oro Enaharo Dogun Ha Ijoba Gesi Lorun

LONDON—Oro Oloye Anthony Enahoro, igbakeji babasalẹ Ẹgbẹ Afẹni eni ti awọn wa si Nigeria lati ilu Oyinbo ni ọsẹ ti o kọja ti di egungun hi awọn alakoso Ijọba Gẹẹsi lọrun titori O inbo ... re, Ọgbeni Dingle Foot, ti nwọn ni ko gbọdọ wa si Nigeria lati wa ba ṣe ejọ rẹ mọ.

( Wo yoku loju ewe kejo )

## Ipade Addis Ababa Kamama : "Alafia Ilu Afirika Ni A Nwa"

ADDIS ABABA—Ipade awọn olori Ijọba awọn enia dudu ti o bẹrẹ ni olu ilu Ethiopia lati akan bi ijẹrin yio pari ni ọla ọjọ ọsẹ. Ipade na kamama nitoripe awọn orilẹde bi ọgbọn ni nwọn peiọ sinu ipade nla na lati jọ jiroro bi awọn yio tiṣe jọ mu rin ti ija ko fi ni jẹ awọn mọ gegebi orilẹ-ede olominira.

( Wo yoku loju ewe kejo )

## Ibukun Ni Ira iti Awon Olododo



Ni ọjọ kejilelogun oṣu May 1946 ni ba ti wa, Ọgbẹni Lamidi Thompson, ẹniti ... awo awọn rẹ yi jalasi ni ilu Eko, ... si ... ni ijọ kẹta May 24. O di ọdun MẸTADINLOGUN nisinsinu oṣu yi ti baba oninure na jalaisi.

Nisu awọn ọmọ ti o fi silẹ laiye ni Muraina A. Thompson, ọga agba nina ile ifowo pamọsi (Banki) kan ni ilẹ yi, Taju Akintola Thompson, Managing Director Eleti—Ọfẹ ati Iya ... Nusiratu Thompson. Baba oninure, ma ẹ jikun, maṣe jẹ ekolo, ohun ti awọn nje ni ajule ọrun ni ki o ma jẹ. Ọpomọja—alegan, Ọrun rẹ!


LAGOS RACE CLUB

First Day

JUNE RACE MEETING

TODAY

First Race at 3.30 p.m.

Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets. 1st will be paid £2 10/-, 2nd £1 10/- and 3rd 10/-.

COME ONE COME ALL

Hon. Secretary,
Lagos Race Club



**Aworan yi ni ti awọn alejo meta ti Ijọba Gesi gba, nigba: ti won wa ni ile–ise ti won gbe nse okun ni Ariwa Ilu Oyinbo lati wo iru ohun elo ti o wa lati Tanganyinka: Ni egbe otun Ogbeni H.B. Mohammed lati Tanganyinka, ekeji si egbe otun ni Ogbeni E.K Lottin lati Kamerun li egbe osi ni Ogbeni A Sahabi lati ipinle Ariwa Nigeria. Won yio wa ni Ilu Gesi fun osu meta fun eko.**

## Coker Omo Ilewe Wo Ewon Lori Wayo

ILESHA — Adajọ Kotu nla nibi ju ọmọ ilewe giga kan ti orukọ rẹ njẹ Roland Coker si ẹwọn oṣu mẹfa fun agbeda ti o gbe ọpọlọpọ enia ni agbegbe Ilesha mọ Ile Ifẹ.

Gẹgẹbi irohin ti a ri gba nipa ejọ ọdaran na awọn ọlọpa ni ọdaran Roland jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ile iwe giga ti nwọn da duro nigba kan nitoripe nwọn ko ri owo ilewe san.

Gbara ti o ti kuro ni ilewe na ni o ti lọ si agbegbe Ilesha lati ma sọ fun awọn enia wipe on ti di ọga iṣẹ ni ọdọ awọn Oyinbo elepo, nitorina awọn fẹ mọ awọn ti o ba ni ilẹ ti nwọn le gbe fun a ti kọ ile epo si.

Ọdaran yi tun gba owo lọwọ awọn ti o nfẹ iṣẹ lọ jaburata.

# Ile Gogoro Tilu Oyinbo



Ni Ilu Oyinbo ni a nkọ ile gogoro ti bẹrẹ; aworan eleyi ti e nwo yi, a-wo-ju-fila-silẹ ni. Bi o ba gun ori rẹ tan o le mọ wo ilu Ifọ tabi Shagamu bi eniti o nwo Ebute-Metta lati Eko. London Hilton ni oruko ti awọn ti o kọ ile ero na pee, on si ni ile-ero (Hotel) ti o tobi julọ ni ilu Gẹsi o ni iyara bi ladẹrin, o si gba enia bi ẹdẹgbẹrun, Ibiti o le ṣe aṣeyẹ fun ọre rẹ ki ẹ ma jo ki ẹ ma yọ wa ni oke patapata.

# Adajo Gbewa Odun Merin

IBADAN — Adajọ agba Ipinlẹ Iwọ Orun, Ọlọla Samuel Quashie—Idun ju adajẹ Kutu awọn ọlọpa kan ti orukọ rẹ njẹ S.A. Adewusi sẹwọn ọdun mẹrin fun owo Ijọba Ibilẹ Idaure ti o ko jẹ.

Nwọn ti wa lẹnu ẹjọ Ọdaran yi ti pẹ, ṣugbọn nkan pato ti a gbọ lori ẹsun ti awọn ọlọpa mu adajọ Adewusi si ni wipe o ko ẹgbaji pọnua (£1,000) owo ilu jẹ.

Gẹgẹbi irohin ti a ri gba latọdọ akowe onirohin wa, Adajọ ni ọdaran Adewusi ri ni Ipinle Ila Orun, lẹhin ti o kuro ninu iṣẹ adajọ nwọn fi si ẹnu iṣẹ awọn BAMIKỌLE ni Ibadan (Western Nigeria Housing Corporation) lẹhin eyi o di alaga ile igbimọ ibilẹ Ijọba Idanre.

Gẹgẹbi alaga, o ni anfani ati ma mọ bi owo ti nwọle si fun ijọba ibilẹ na. G ogbo owo gbese ti awọn kan fi iwe banki san fun Ijọba ibilẹ Idanre, a pa-sapo ni ọdaran yi ṣe wọn.

Awon Iwe Asiko:

# Amoju Ni Yio Ba Ekun Sare Je

### B'ori

AKIYESI : Ninu itan na ti a da fun eyin okawe wa ni ose to koja, gbogbo ..in e ti ka bi Sare ti pade agbako ekun kan loko ti o lo a ti bi o r i re se yo ninu ewu na, ki awon ebi r e to gbaa nimoran wipe ki o bo ori re. Iyoku itan na niyi:

### Lati Owo AKOWE

Ni aro kutukutu ijo keji, gbogbo awon ebi Sare dawo ojo, nwon si lo ra obuko ti o ti nsun ife lati fi bo ori Sare. Lehin eyi aya re ati awon eb re ti nwon ri je mu akuko lowo, elomiran m u agbebo, elomiran mu eiyele ti nwon fe fi bo ori Sare.

Nigbati gbogbo ese ebi ati ore pe, nwon pe Sare si arin ita agbo ile, nwon ni ki o wa so ti enu re, ki o si sure fun ori re ti o yo o, ti ko si jeki ekun ki o pa a je.

### Apejuwe

Bi Sare ti bere ire su ni o nse apejuwe ekun na. O ni, "Bi mo ti nroko lo, iwaju ti ngo si wa ni mo si ekun na ti o to kabitikabiti, ti o fiu kalakinni, ti o si mbo wa sodo mi taro, ti o si nka ila je panun, panun.

Awon enia ti nwon mo pe ekun ki ije ila ni 'Ha! Bi eranko ti o ri, ti o fin kalakinni ba nka ila je panun ki se ekun; nitoripe ekun ki ije ila; eran ni ekun nje. Igala ni o ri ti o npe ni ekun."

### Amoju

Nigbati awon enia gbo eyi, ni gbogbo won ba tuka pelu asogbo pe 'Igala ni Sare ri li oke ti o npe ni ekun.' Awon ebi to ta obuko wo ., nwon si pin owo re; awon ti nwon m u akuko tabi eiyele so won sile, nwon si bu agbado fun won pe ki nwon ma je lo, gbogbo enia si tuka.

Oju Sare papa da, o si nwo ile gbu. Lati ojo na ni awon enia iti ma pa owe pe, "Amoju ni yio ba ekun Sare je"

# Kora Ti Nwon Le Kuro Nilu Tun Pada

KANO—Awon olopa mba arufin Oyinbo Kora kan, Mohammed Nooradeen Ibrahim, en odun metadinogbon, ti nwon ti i igba kan le kuro nilu sejo wipe o tun wo ilu wa lai gba ase lowo Ijoba.

Nigbati awon olopa wo odaran Kora na de iwaju Adajo Kotu, nwon ni o ti to odun meje gbako nisisiyi ti awon ti le okunrin na kuro nilu wipe ko gbodo pada si ile Nigeria mo rara. Nwon ni o si ya awon lenu ti awon tun ri laipe yi, ti o tun wo ilu pelu iwe-ase (passport) tuntun.

Odaran na ni iro ni nwon pa mo on, enikan ko fi igba kan so fun on wipe nwon ko fe on nile yi mo rara, o ni on funra on ni on kuro ni Nigeria lati lo se ile wo ni Beirut.

Loya ti kora na gba ni awon olopa so fun un lasan wipe ti o ba mbo wa si ile yi ki o ma mu iwe-ase ti o dara lowo. Nwon ti sun ojo ejo re na siwaju.

# Awon Olosa Kowe Si Oga Ile Iwe

PORT HARCOURT—Awon egbe olosa kan ti nwon sese wo agbegbe ibi, ti nwon nfi ibon dara kiri, ti kowe aragbadu kan si oga ilewe awon Aguda kan ti nwon npe oruko ile-iwe won ni Immaculate Heart Catholic Commercial School wipe ki o mura sile de awon, laipe yi awon mbo wa ko ijewe re patapata.

( Wo yoku loju ewe kefa )

Irohin Kakiri Agbaiye ...

# Igbe Orin Npa Ara Burma

Arun igbe-orin ti be sile ni ilu Burma, o si ti pa to ogorun enia nisisiyi ni ilu na, Ni ilu kan ti awon npe ni Moulmen, gbogbo ilewe ti n w o n nko awon omo leko a t i ile ise ijoba ni nwon ti ti hamu-hamu.

Igbe-Orin na ..... lose pupo to bee ti awon akowe wole-wole ti pase wipe ki nwon ye onje ilu Moulmein lo si ilu miran ati pe ki nwon ye m u omi inu gangan ati o m i inu ogodo.

Awon omo Egbe Alagbelebu Pupa (Red Cross) ti dide si oro ajakale-arun igbe orin yi, nwon ti fi opolopo egbogi ti awon a lo fun awon ara ilu ki arun na ma ko lu w o n aruse si won.

## Alikali Ju Eniti O Gbe Ore Re Lowo Se'won

KADUNA — Alikalu Kotu kan ju odaran kan, Gabriel Robert, ti o lo gbe owo osu ore re ,sewon osu mefa pelu ise a se kara.

Gbara ti odaran yi ti ...bo wipe ore re, Gabriel Asyanti ti o ngbe adugbo kan ti nwon jojo se ti gba owo-osu re ..i o ni lo lati ki i

Nigbati odaran ... i de ibe ore na se ... a ejo daradara, ... nigbati o nlo gbogbo ... mesan, ... san ... Asyanti ... yiy yda... e n yiji gbe lo patapata.

# EETI—OFE

NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMS

28, Kosọkọ Street, Lagos, "EЬETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL XIV. NO. 870 SATURDY MAY 25 — MAY 31 1963


## Oro Olotu:

# Tani A Ri Ba Wi?

Iwe ikilọ kan ti a gbọ wipe nwọn tẹ jade lati ile iṣẹ Minis ta alamojuto eto ẹkọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ibadan ninu ọsẹ ti o kọja si awọn Tiṣa olukọ ti nwọn nkọ awọn ọmọ wa lẹkọ wipe ki nwọn ye le wọn kuro nilewe mọ ti nwọn ko ba yege ninu idanwo ọdọdun ti nwọn ma nṣe; iwẹ ikilọ na dun mọ wa pupọ ti a fi kan saara si awọn ti o gboju gbaya lati gbe iru ikilọ bayi jade. Nwọn ṣe pupọ.

Ko si nkan ti o wa ti ko ni ni ibẹrẹ tirẹ. A ro wipe ko ju ọdun mẹsan ti awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ na da eto ẹkọ ọ'ẹ yi silẹ kakiri Ipinlẹ na. Nigbana ko sawọn olukọ tobẹ ti nwọn le kọ awọn ọmọde lẹkọ ninu awọn ilewe ti nwọn fẹ da silẹ na; ko si si ile ti nwọn yio ko awọn ọmọ na si lati kọ wọn lẹkọ yi; ikẹta, awọn ti ko ba tun ie alatilẹhin fun eto ẹkọ-ọfẹ yi ẹnu atẹ ati abuku ni nwọn mbu luu.

## Baba T'oFomo Loko Loru

Nwọn nsọ fun gbogbo awọn ara ilu kakiri wipe eto ẹkọ-ọfẹ ko dara fun ilu rara. Awọn ẹlẹgan naṭmọ da ju wipe ni gbogbo ilu awọn Oyi gbo nibiti nwọn ti gbe ilaju wa, ọfẹ ni Ijọba nkọ awọn ọmọ wọn l'ẹkọ.

Owo kekere kọ ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun na si eto ẹkọ-ọfẹ yi. Ijọba Ipinlẹ miran da a ni aba o tẹ sii, ada ati kunmọ ni nwọn fi yanju eto ẹkọ-ọfẹ yi ni Owerri mọ Enugun mọ Onitsha. O yẹ ki eleyi jẹ ẹkọ fun gbogbo wa ki a fi lakaye gbe ọrọ eto ẹkọ-ọfẹ yi nitoripe orire ni Ijọba Ipinlẹ wa gbe wa fun wa.

## Ti Koju Ki le Mo

O ye ki a tun ṣe ikilọ fun awọn olukọni ti nwọn gba kakiri Ipinlẹ Iwọ Orun ti nwọn ko fẹ fi tara tara ṣe iṣẹ, ti nwọn sọ gbogbo ọrọ na di ọga ta, ọga ko ta, owo alarobọ ni lati pe. O yẹki awọn olukọ ni mọ wipe iṣẹ ti a pe wọn si kiṣe iṣẹ yẹyẹ rara, iṣẹ ti nwọn le fi gbe ilu wọn ga ni, o si yẹ ki nwọn ma kọ awọn ọmọ ile iwe wọn ni ẹkọ ti ojinna ti nwọn fi le yege nibikibi ti nwọn ba lọ fun idanwo lori ẹkọ ti nwọn ti kọ wọn.

Lẹkansi a tun kan saara si awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti nwọn paṣẹ wipe ki awọn ọga ilewe ye yọ awọn ọmọ ni ile ẹkọ nitoripe nwọn ko yege ninu idanwo ọdọdun ti nwọn nṣe.

Nitotọ ejọ kiṣe ejọ awọn ọmọ ilewe yi. Tani a ri ba wi bi awọn ti ... alara paapa ti nwọn fi ọmọ lọkọ ni oru ti nwọn ... ko jẹ ki ilẹ mọ.

# Iwe Si Olotu

## E Ye Mu Siga Ninu Moto

Ẹ jọwọ Olotu, ẹ ba wa tẹ si eti gbọ awọn ero ti nwọn nwọ mọto-akero bi bọsi (bus) tabi bọlẹkaja ti nwọn nku efin siga gbula pe o lodi si ofin lati ma mu siga ninu mọto-akero.

Ti a ba sọ fun awọn baba onisiga yi wipe siga mimu ninu mọto lodi si ofin, nwọn a ni ki a gbẹnu wa sọhun. Ọpọlọpọ awọn oni mọto bọsi ni nwọn tilẹ lẹ iwe ikilọ nipa siga mimu yi mọ inu mọto wọn.

Mo gbọ wipe ẹnikẹni ti oba ru ofin a nmu siga ninu mọto yi ni ilu Ghana, owo nla ni yio san si Kotu. Ti awọn Ọlọpa wa ba mu ọkan ninu awọn baba onisiga yi awọn yoku a fi kọgbọn.

Ẹ ṣe aye ti ẹgba mi, Olotu, iwaju ni ẹo ma lọ.

Emi ni,
Mushin Jimọ Alabi

## A Nfe Awon Olopanu Kakiri

A gbọ wipe awọn ọga Ọlọpanu ṣẹṣẹ da awọn ẹgbẹ Ọlọpanu kan silẹ ti nwọn ko gbọ sunsun. Ẹ jọwọ ẹ ba wa tẹ mọ wọn leti ki nwọn pin awọn ọlọpanu na kakiri ki o mọ jẹ ilu Eko nikan ni nwọn yio wa.

Ilu bi Ibadan, Kaduna, Ilọrin, Kano, Aba, Port-Harcourt ati Enugu ... wa nibẹ. Awọn ọlọpa ati awọn akọwe ti o ngba owo riba kun inu Kotu awọn ilu yi jaburata.

Ko wu awọn dẹrẹba Oni-mọto paapa lati ma fun awọn Ọlọpa yi ni owo ẹhin, sugbọn ti nwọn ba kọ lati fun wọn, awọn ọlọpa yi a ma kana mọ wọn, nwọn a ma wọn ni imukumu.

Ẹ jọwọ a nfẹ awọn ọlọpa'nu yi kakiri ni Nigeria.

Agbokojo Emi ni,
Ibadan M. Akinlabi.



Ọgbẹni Walter M. Schirra ti ẹ nwo aworan rẹ yi ni ẹnikarun ti awọn Ijọba ilẹ Amerika kọ ran lọ si oke sanmọ wipe ki o lọ wo bi ọhun tiri. Aṣọ ti o yatọ pupọ ni nwọn da fun un fun irin ajo si orun na. Ọgbọn ti wọnu ọgbọn, nwọn ti tun fi nkan alarabara si aṣọ ti Ogbeni Gordon ayọrunbọ ti o lọ siru awọsanma laipẹ yi.

# Nihin ohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

### Owo De!

O ye ki mba enyin ọmọ ilẹ Nigeria yọ lọkunrin ati lobinrin fun irohin nla kan ti mo gbọ wipe Oloye Festus Okotie-Eboh mu wa fun yin nipa iwe-owo pepa (Currency notes) ti nwọn yio ma tẹ fun yin. Ẹnyin Ọrẹ mi, OWO DE!

Ọrọ yi kişe yẹye: mo gbọ wipe kişe owo-pepa nikan ni ao ma tẹ nilẹ yi, a o tun ma rọ owo şile rẹlu, a o si da agbedẹ awọn tọrọ ati kọbọ kọbọ silẹ. Boya eleyi le mu ki owo awọn lagerọ dinku, emi ko le, sọ şugbọn pẹlẹpẹlẹ di ọwọ wa o.

## Burọda Ile-Owo

Ọrọ pọ rinu nkan ti o jẹki nsọ wipe pẹlẹpẹlẹ di ọwọ wa. Nitoripe nkan ko ti to eyi a-pa-sapo ti pọ ju lọwọ wa nilẹ yi, ki a jọwọ ki a ma şe eleyi ni a-pa-sapo o.

Laipẹ yi, ao ma gbọ orişirişi orukọ bi Burọda Ile-owo, Bab Ile-owo ati Aunti Ile -owo. Akọwe ile-owo. paapa gbọdọ şora ti nwọn ko ba fẹ ki ile ẹwọn Kirikiri lun ni Ajegunlẹ tabi ni Enugu.

## Ijebu D'Abule

Bi ọrọ owo ko ti şe yẹyẹ to mo gbọ wipe olukuluku awọn enia ni nwọn ti nkọwe si Oloye Okotie-Eboh wipe ki o jọwọ ba awọn wa işẹ sibi ti nwọn gbe fẹ lati ma tẹ owo-pepa yi. Mo gbọ wipe awọn ara ilu Ijẹbu ti bo ti awọn Urbobo molẹ, ti awọn ara ilu Abakaliki mọ Aba tun pọ janrẹrẹ. Awọn kan ni Apapa Ajegunlẹ ni o yẹ ki nwọn kọ ile owo-rirọ na si.

Ọrẹ mi, owo de fun awon alagbẹdẹ a-ji-rọ-tutu ilẹ wa, şugbọn ki nwọn mọ wipe Ijẹba ti kọle mọ, le ni ọgba ẹwọn ni Kirikiri ni Apapa Ajegunlẹ na nitoripe owo ti a fẹ ma rọ yi kişe owo-a-pa-sapo rara.

## Ogun Abisinia

Lati ọsẹ ti o ti kọja lọ ni ọba ilu Abisinia, Ọlọla Haile Selassie ti bẹrẹsi gba alajo awọn Olotu ilu olominira ti Afirika lọtun losi. Ilu Abisinia yi ti gb'ominira ti pẹ şugbọn ni iwọn nkan bi ọdun mejidilọgbọn awọn ara ilu Itali fẹ gbe nkan kọja lori awọn ọmọ ilu Abisinia tobẹgẹ ti ọrọ na fi di ogun ti a npe ni OGUN ABISINIA nigbana lọhun.

Oju Ọba Abisinia yi ri nkan nigbana, gbogbo awọn ilu Afirika gbogbo ti ko ba si ran an lọwọ, oko-ẹru ni awọn na si wa. Gbogbo ipade awọn alagbara aiye igbana ti nwọn npe Ọba na si ẹhin awọn alawọ funfun ẹgbẹ wọn ni nwọn wa. Bi o ba di oni ti Ọba yi ba pe awọn aladugbo rẹ, awọn ara ilu Afirika olominira jọ'ko kuna rara. On na ti mọ wipe a-gbajọ ọwọ ni a fi nsọ aya.

Ọba Abisinia, mo ki yin ẹ ku alejo, Ọlọrun ki o fun yin ni suru ti ẹ o fi tẹ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ yi lọrun.

## Onigbagbo Amerika

Ọrọ Ogun Abisinia yi mu mi niran ogun abẹle ti awọn Oyinbo alawọ funfun ilu Amẹrika mba awọn enia dudu ọdọ wọn ja nisisiyi nitori awọ ara wọn. Mo gbọ wipe onigbagbọ gaan ni awọn Oyinbo ara ilu Amẹrika yi şugbọn igbagbọ ti nwọn yatọ; igbagbọ ti wọn ko kọ wọn wipe ki nwọn ma fẹran ẹnikeji wọn bi ara wọn.

Ni ilu Alabama ni Amẹrika bi o ba jẹ enia dudu, Şọşi tirẹ wa lọtọ. Ẹ jọwọ, ẹnyin ẹgbẹ Serafu ati Kerubu, ẹ da owo jọ, ki ẹ lọ şe iwaşu fun awọn Oyinbo ilu Amẹrika nitoripe KAFERI ni wọn patapata.


# E Polowo Oja Yin sinu iwe irohin Eleti-Ofe ti o kun fun irohin aladun.




## Ọga Scout Nigeria Ta Scouts Gesi Lore

Laipẹ yi ni Awọn Ọga Scout ilu Gẹsi meji gba iwe ẹyẹ kan lọwọ ọga Scout Ipinlẹ Ariwa, Mall m Ayọ Bello (ti o wa ni apa osi aworan yi) ni ilu ti nwọn npe ni Newcastle-Upon-Tyne. Eleyi ni orukọ awọn ọga ẹgbẹ Scout na ti nwọn fi igba kan ko awọn Scout ọmọ ilu Gẹsi wa si ilẹ Nigeria: Ọgbẹni Kenneth Smith (on ni o şe ekeji ni apa osi) Robert, Armstrong (ẹnikẹta ni apa osi), Ẹnikẹrin ti o wa ni apa ọtun ni Ọgbẹni P. Denham.

## Minisit Kan Ni Ki Nwon Gba Awon Omolewe TiKo Yege Pada

IBADAN — Minisita alamojuto eto ẹkọ Ipinlẹ Ijọba Iwọ Orun, Ọgbẹni B. Olowofoyeku, ṣe ikede laipẹ yi fun gbogbo awọn ọga ile ẹkọ ati ile ẹkọ ti nwọn ti nkọ awọn Tiṣa wipe ki nwọn gba gbogbo awọn ọmọ ilewe ti ko yege ninu idanwo ti nwọn ṣe kọja pada si ile eko wọn

Minisita na ni o n gbọ irohin wipe ọpọlọpọ awọn omo ile ẹkọ yi ni nwọn ti le kuro ninu ile ẹkọ ti n on nlọ, o ni o yẹ ki won tun fun wọn laye ki nwon tun gbidanwo ọdun kan si.

Minisita na tun ṣe alaye wipe aiyege awọn ọmọle-we ṣe ẹbi wọn, ẹbi awọn ẹbi awọn tiṣa wọn ti ko wọn daradara ni O ni on fẹ ki nwọn wipe awọn ṣẹ-ṣẹ bẹrẹ ẹkọ ọfẹ nilẹ yi ni.

O ni lẹhin ọdun ti nwọn ba ti ṣe idanwo tan, ki nwọn fi gbogbo orukọ awọn ọmọ ilewe ti ko ba yege ninu ekọ rẹ ranṣẹ si ile iṣẹ awọn ni Ibadan, awọn yio mọ ọna ti awọn yio gbe e gba.

## Awon Olosa Kowe Si Oga Ilewe

Akọwe onirohin wa ni oga ilewe yi nikan kọ ni awọn ọlọṣa na kọwe si nwọn ti tun ha iwe 'a mbọ, ẹ ma palẹmọ silẹ de wa" fun awọn olowo onisowo ti nwọn wa ulu yi. Awọn ọlọṣa na ni gbogbo iie ti uwọn ntaja ati ile wọn ni awọn yio ko patapata.

Ni oru ijẹta ni awọn ole na yinbọu si awọn ọdẹ aṣọ ta meji kan ti uwọn usọ agbegbe kan Diobu, ti uwọn si ṣe wọn lese. Salami Ogundipẹ ati Augustus Nwachukwu ni orukọ awọn aṣọde mejeji

A tun gbọ irohin kau lati Awka wa wipe awọn ole kan ṣyinbọn pa Anthony Ezanwanne, tiṣa-agba ilewe Aguda ni Ekwunobia nig ba-ti o jade loru wa si Ita lati inu ile rẹ lati tọ.

## Awon Ole Ti Nwon Kowe Ti Ri Se

Port-Harcourt–Awọn Ọlọṣa kan ti nwọn ṣẹṣẹ de agbegbe ibi, ti nwọn nkọwe si awọn olowo ati onisowo kakiri wipe awọn mbọ wa ko ile wọn ti ri ṣe ninu ile awọn oyinbo onişowo kan, awọn alagbọn, nibi. Gbogbo ẹru ti nwọn ri ko nlọ bi ẹlẹdẹgbarin pọnun (£7,000) tabi ju bẹ lọ.

Nwọn ni gbara ti awọn ogunlọgo awọn onişowo yi ti ri iwe awọn ọlọṣa ti nwọn npe ara wọn ni PADI yi gba ni awọn ọlọpa ti bẹrẹsi feti leko kakiri, ti nwọn si n ọ'le sọ ọna.

Sibẹsibẹ awọn Ọlọṣa na ri ṣe lara awọn onişowo ilu Port-Harcourt. Ni eti ọja ilu na, gbogbo ẹru ti o mbẹ ninu ṣọbu awọn Oyinbo India kan ni nwọn ko tefe tefe. Mo gbọ wipe ọwọ awọn ọlọpa'nu ti tẹ diẹ ninu eru ti nwọn ji ko na ṣugbọn nwọn ko ti ri ẹnikan gba nu.

Awọn ọdẹ aṣode meji ni awọn ọlọṣa na yinbọn fun ni Diobu laipẹ yi nigbati nwọn nlọ jale wọu

## Awon Olopa Ngba Ibon Lowo Ode Otta

ỌTTA — Awọn ọlọpa ti ṣe ikede fuu gbogbo awọn ọdẹ ilu Ọtta, Ilogbo ati agbegbe rẹ wipe ofin jade wipe gbogbo ẹnikẹni ti o ba ni ibọn nile tabi loko ni, ki nwọn ko nwọn lọ si ọdọ awọn ọga ọlọpa ni A'ẹokuta nitoripe awọn ko gbọdọ ri ibọn, ati ẹtu lọwọ ẹnikan mọ nira in ilu Ọtta ati arọko.

Ninu iwe ofin ti o jade l'Eko lati ọdọ awọn Ol. tu Ijọba Apapọse, nwọn ni ẹnikeni ti nwọn ba ri ibọn tabi ẹtu ibọn lọwọ rẹ ni ilu Ọtta lati ọsẹ yi lọ awọn Olọpa yio ba Oluwa rẹ ṣẹjọ, yio san ẹdẹgbẹta pọnun (£500) tabi ki o lọ ṣẹwọn ọdun meji gbako.


Never refuse a trial run before you choose a car. Let the cars speak for themselves and be scrupulously critical when looking at different models. We are convinced (from long experience) that any Mercedes-Benz will pass such an examination with top marks. Please give us the opportunity of substantiating our claim.

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.
Lagos . Ibadan . Kano . Kaduna . Jos . P. Harcourt . Aba

Sub - Distributors:

ARMELS TRANSPORT LTD.
Benin City . Onitsha . Aba

# New International Students 'Hotel' For London

LONDON—A self suppor-ting international "hotel" costing nearly £900,000 to give overseas students a residential and social centre in London was to be built immediately, the Earl of Euston, Chairman of the Council of the International Students Trust, announced in London yesterday.

The house, to be built near Regent's Park, should be ready for occupation toward the end of next year and is designed to provide hostel accomondation for 135 resident stubents, dining room facilities to serve up to 1,000 low cost meals a day an assembly hall for 350 and six meeting rooms as well as writing, reading and games.

The British Government has agreed in principle to give £55,000 in support of the hostel.

## Bahamas For Self Government

LONDON—The Dahamas the three thousand British islands extending over 550 miles of the Caribbean are to have a two-chamber legislature with a ministerial system of internal self-government, probably by Is January, 1964.

The proposed new constitution was announced yesterday following a London conference.

The report of the conference, signed this week, is expecten to be published soon as a Government White Paper.

## Cement Works at Apapa Soon

LONDON-Electrical equipment for one of Nigeria's new cement industries is one of several orders for developing Africa now being uudertaken by the South Wales Switchgear Company of Monmouthshire, which has concluded an agreement to train some of Nigeria electrical engineers.

The company is assembling the transformers and Switch boards for the Electricity Corporation of Nigeria which will supply power for the new cement work at Apapa.

Similar equipment — all designed to withstand tropical heat and humidity—is being made to distribute power in rural areas of Uganda and to supply electricity to a fast-growing area of Nyasaland.

A training scheme between the W ish firm and Nigeria has been finalised where some of Nigeria's most promising engineering students will be trained in South Wales and similar arrangements for to sight apprentices a year from Uganda are being worked out between the British firm and the Uganda authorities

## Nigeria's Women's Champion To Set New Records

LONDON—Nigeria's 100 yards and 220-yards women's sprint champion Miss Clarice Ahanotu is planning to set new records when she return from eight months, study in britain in August

"I have been doing a lot of training while studying at the Dartford College of Physical Education, with a fellow student Ann Packer, who is the leading contender for the British sprint championship," said Clarice, who was granted a British Council bursary to go to Britain.

"I have also run for Dartford in athletics matches with other colleges in the London area.

Clarice, who has held the Nigerian sprint championship since 1959, went to Britain to study athletics coaching. She hopes to get a coaching job in Enugu when she returns home.

"Coaching in a very difficult business," she said, "at times your athletes may not respond, no matter who you may want them to, yet you cannot force them."

Now that most of her studies are over, Clarice hopes to get more serious competition experience in Britain in meetings organised by the Amateur Athletics Association, before she returns.

Read And Advertise
In the Eleti-Ofe Weekly News Paper



## Cheif Education Officer of Lagos Starts Course In Hull, England.

Mr. Dahunsi (second from right), who is Chief Education Officer of Lagos was welcomed by the civic head of Hull, northern England, when he arrived to start a six-month study course With him in this picture are (left to right): Mr S B Hobson (Cheif Education Officer), Alderman Science (Chairman of the Education Committee), and Alderman Frear (Lord Mayor)

## Ijoba Togo Da Awon Minisita Sile

LOME—Ilu Togo ni titi ni ana nigb ti awọn ara ilu na gbọ irohin wipe Ijọba wọn da awọn minisita marun ti nwọn ti lọ fi pamọ si aja ilẹ sile wipe ki nwọn ma lọ sile wọn.

Orukọ awọn minisita marun na ni Ọgbeni Freitas, Hospice Coco (Minisita alamojuto eto ile owo,) Paul Amegee (Minisita alamojuto ile kikọ,) Martin Sankaredja (minisita eto ẹkọ) ati N. Karamoko (minisita alamojuto nkan ọgbin).

Gbogbo awọn ilu ni nwọn si ti nba awọn minisita na yọ wipe nwọn ku orire. Onirohin wa ni akọwe agba kan ninu ile iṣẹ Ijọba Togo ṣe alaye fun on wipe nkan ti o fe ki awọn da wọn silẹ ni wipe aya ilu ti ba lẹ, ko siwahala mọ.

## Oro Enahoro Degun

( O berẹ loju ewe kinni )

Ni ijẹta ninu ile igbimọ awọn aṣofin ilu Gẹsi, obinrin kan ti orukọ ujẹ Barbara Castle (ọkan ninu awọn a atako) ni o ko bere wipe iru ileri wo ni Ijọba Apapọ ti ilẹ Nigeria ṣe fun Ijọba Gẹsi lori ọrọ Oloye Ẹnahoro, ki o to di wipe nwọn fi Oloye na-le IjọbaNigne a lọwọ.

Akọwe eto arin ti Ijọba ilu Gẹsi, Ọgbẹni Henry Brooke nitotọ awọn Oloye ti Ijọba ilẹ Niger a ji ọrọ na sọ fun on wipe awọn ko ki gba fun awọn lọya meji Dingle Foot ati Gratiean si pe ki nwọn wọ ilu lati ba Oloye Ẹnahoro ṣe ẹjọ ti awọn ọlọpa mba ro.

Eleyi ni o mu ki Olori awọn alatako ti Gẹsi, Ọgbẹ in Harold Wilson fi aake kori wipe ẹgbọn ẹtan ni Ọgbẹni Brooke lo fun awọn ki o to sọ wipe dandan awọn ni lati Oloye Enahoro pada si ilẹ Nigeria ni. Ọgbẹni Wilson ti fi iwe-ibawi ti awọn fẹ fi ba akọwe eto arin ilu Gẹsi na wi ranṣẹ si aiaga si ile igbimọ awọn aṣofin nitoripe iru arun bayi ko ṣe ọmọ lọwọ awọn ri.

## Ara Popu Ko Da, O Gbadura Fun Araiye

ROME — Go[illegible]gbo awọn Ijọ Ṣọsi Aguda kakiri agbaiye lokunrin ati lobinrin, lọmọde lagba ni nwọn ngbadura fun Ẹni-ọwọ Pope John ti amodi fere nse lọwọ lọwọ yi.

A gbọ pe [illegible] gbo oginlọgọ awọn enia ti nwọn wa si Ọgba Aguda ni Pope na gbadura fun ṣugbọn ko si a nghe ọwọ le wọn lori mbe.

Agba ti de si Ẹni-ọwọ Pope John nitoripe o ti di ẹni ọdun mọkanlelogorin nisisiyi, gbogbo awọn enia ti o si ri nibiti o gbe ng [illegible] dura fun awọn araiye ni [illegible] o mu wipe ọjọ [illegible] de [illegible]

Lati ijẹta ni Ẹni-ọwọ na ti ṣẹle adura, ti o si ngba ve, ki enikẹni to tun le fi ojo kan si to ijọ medọgbọn. Ni ọjọ Ọṣẹ (Sunday) June 2nd ni yio ṣe isin Igokerorun.

## Olopa Ko Awon Obinrin Ti Ko Loko Ni Zaria

ZARIA — Awọn dongari Ọlọpa Zaria da si arin Sabon—Geri ati Tudun Wada lati ma kọ awọn obinrin ti ko lọkọ ti nwọn nṣe iṣẹ agbere. Ni ọsan ana, awọn ti nwọn ri ko to adọta enia.

Gbara ti awọn ọlọpa na ti bẹrẹsi ko awọn obinriin ti ko lọkọ yi ni ọga awọn ọlọpa na ti fi ẹro gbohungbohun sọsọ si Ọga Ọlọpa Oyinbo (wipe ko fuu on ni ọlọpa si, nwọn si fi mọto mẹta ko awọn ọlọpa wa lati ran awọn dandoka lọwọ.

Ọrọ ti a gbọ nipa kiko ti awọn obinrin na ni wipe gbogbo wọn ni nwọn nko awọn ọlọpa pa[illegible] si. A gbọ wipe awọ ọlọpa ni awọn yio ba wọn ṣẹjọ ni K o t u niwaju adajọ agba ni ọtunla ọjọ Aie; nwọn ko gba iduro w ọ n rara.

## LAGOS RACE CLUB

SATURDAYS 25th MAY. 1st, 8th, AND 15th JUNE, 1963.

Racing Starts at 3 00 p m. each day of the Meeting

DECLARATION

Declaration will be made at the Secretary's Office between the hours of 1.30 p.m. and 2 p.m. on Racing Days

ADMISSION: 3/- PER DAY, including Entertainment Tax

CHILDREN

No Children under the age of 14 years will be permitted to enter the Members Enclosure.

SWEEPSTAKE

On each day's Race Meeting a Sweepstake will be drawn on the number of Admission Tickets. 1st will be paid £2 10/-, 2nd £1 10/- and 3rd 10/-.

## Ipade Addis Ababa

(Oberẹ loju ewe kinni)

Ọlọla Ọba Haile Selassie ni o ṣi ipade na, o si sọ ikan ko jokau ọrọ fun gbogbo awọn ti nwọn pejọ si ajọ ipade na. Ọba na ni on fi alajọbi bẹ gbogbo wọn ki nwọn wa ni irẹpọ, ki awọn si se iṣẹ ni gidi ki awọn le gba awọn ara wọn yoku kuro ninu ajaga oko-ẹru.

Ọba na ni ilokulo ni awọn alawọ-funfun n l o awọn enia dudu ti nwọn wa ni ilu bi Rhodesia, Angola, Mozambique ati Isalẹ Afirika. O ni ko si ọmọ ilu Afirika ti o jẹ so wipe iwa buruku ti nwọn nhu si awọn enia dudu ni Isalẹ Afirika (South Africa) dun mọ on rara.

Ẹniti o tun sọrọ ni apejọ na ni Bal[illegible]ilu Liberia, Ọlọla Tubman, o ni on ri wipe ọkan lati fi ohun ṣe ọkan ni awọn ba wa sibi ipade na. O ni gbogbo aiye ni o nmi ti ti ko si ifọkanbalẹ fun awọn Ijọba alagbara, o si yẹ ki awọn fi eleyi kọgbọn ki awọn wa bi yio ṣe tu, ti yio ba fun awọn ni Afirika.

Olotu Ijọba Nigeria, Alhaji Tafawa Balewa gba iyi o gba ẹyẹ lọjọ ti o gunlẹ si ilu Addis Ababa, gbogbo awọn enia pataki ati awọn ọmọlewe ni nwọn to lọwọ lọwọ lati kii ku abọ, on si ni Olotu Ijọba kinni ti awọn ara ilu Ethiopia kọ tẹ aran pupa silẹ fun wipe ki o gun ori rẹ kọja lati inu ọkọ ofurufu ti o wọ de ilu na.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Phone 23370 Editor, (Olotu) Ola Onatade, 15, KosọkọStreet, Box 467 Lagos.